# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,590 MONDAY DECEMBER 20, 1965 (2D)


## Ọfale Kan Yo Ẹhin Meji Lẹnu Ọrẹ Rẹ Obinrin

STOCKHIM - SWEDEN:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun ogunlọgọ awọn enia ti nwọn wa si ile ẹjọ kekere kan ni ilu Stockhim, ti iṣe olu ilu Sweden nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, Sweden, ẹni ọdun mẹdogun ti awọn Ọlọpa mu wa si ile ẹjọ fun ẹsun wipe, o gbiyanju lati pa enia, o si tun da ọgbẹ si enia lara ni gbangba ode ni Opin ọsẹ ti o kọja lọ yi.

Ọlọpa ti oba Ọdaran Ọdọmọdekunrin na ṣe ẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ wipe, ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kedogun oṣu yi ni Ọdaran ọmọdekunrin na pade Ọrẹ rẹ Obinrin, ni oju ọna nigbati ọmọdebinrin na nbọ lati ile ẹkọ rẹ.

Nigbati awọn enia na pade arawọn ni oju ọna, Ọdaran na ba pe ọrẹ rẹ Obinrin sọrọ tan, ti o si fẹ maa lọ si ile, ni Ọdaran na ba pe ọrẹ rẹ wipe ki o to lọ, ki o jẹki awọn mejeji jijọ fi ẹnu ko ẹnu, ki awọn si tuka, ṣugbọn ọrẹ rẹ Ọdọmọbinrin na kọ lati gba imọran rẹ.

Bi Ọdaran na si ti fi ipa mu ọrẹ rẹ Obinrin na lati wipe ki awọn mejeji jijọ fi ẹnu ko ẹnu, ni ọrẹ Obinrin ba

WO OJU EWE KẸFA

## Ija Nla Bẹsilẹ Larin Gomina Ati Akintọla

# GOMINA FẸ TU ILE IGBIMỌ AṢOFIN IWỌ ORUN KA ?

IBADAN:- A ngbọ hunnuhunnu labẹlẹ wipe, edeaiyede kan ti bẹsilẹ larin Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Oloye Samuel Ladoke Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lori abajade ibo ti o kọja lọ yi eyiti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi, ti ibo na si ti da rogbodiyan silẹ yika gbogbo Ipinlẹ na lati ọjọ ti nwọn ti dibo na tan.

Gẹgẹbi Irohin ti a gba ni alẹ ana lati ọdọ Oniwe Irohin wa ni Ibadan, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ ti sọ fun Oloye Akintọla wipe, ki o pe awọn ọmọ ẹgbẹ Ajumọṣepọ UPGA lati lọwọ ninu Ijọba Ipinlẹ Ipinlẹ Iwọ Orun, ki gbogbo awọn ẹgbẹ mẹtẹta- ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹgbẹ Alakukọ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ jijọ ma a ṣe Ijọba,



**Ọlọla Fadahunsi**

Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Ṣugbọn nigbati Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi da imọran yi, a gbọ wipe, Oloye Akintọla lodi si imọran na, o si kọ lati gbọ ọrọ ti Gomina na sọ fun un.

## Ariyanjiyan

Siwaju asiko yi ni Oloye, Akintọla ti sọ fun Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi wipe, ki o pe ipade Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ki awọn ọmọ Ile Igbimọ na le ṣe ipade kini lẹhinti nwọn ti dibo tan ni Ipinlẹ na.

Ṣugbọn Ọlọla Fadahunsi sọ wipe, on ko ni pe ipade na, nitori bi gbogbo nkan ti ṣe nlọ ni Ipinlẹ yi nisisiyi ati gbogbo ohunti awọn enia nsọ lori ibo na pẹlu rudurudu ti o ti bẹrẹsi maa ṣẹlẹ lati igbati nwọn ti di ibo na tan.

Ọlọla Fadahunsi wa ṣe alaye wipe, ki Oloye Akintọla jẹki gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ wa ninu Ijọba na ki awọn to le pe ipade ti o sọ wipe ki on pe.

Nipa ṣiṣe bayi, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn yio ni Aṣoju ninu Ijọba Ipinlẹ na eyiti yio jẹ Apapọ Ijọba, bi awọn ba le ṣe eleyi, gbogbo rogbodiyan ti o wa ni Ipinlẹ na nisisiyi si yio mu ọwọ duro patapata ti gbogbo awọn ara ilu yio si ni ifaiyabalẹ, iṣọkan ati Ijọba rere ni Ipinlẹ yi.

Ọlọla Fadahunsi tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, ninu yiyan awọn ọmọ ẹgbe oṣelu na, gbogbo awọn ẹgbẹ na ni nwọn yio ni aṣoju ninu Ile Igbimọ Ijọba, ti nwọn yio si jijọ pin aye ijoko awọn Minista dọgbadọgba.

Gomina na tun ṣe alaye pẹlu wipe, bi awọn ba le ṣe eleyi, awọn tilẹ le jijọ wa pọ fun nkan bi oṣu mẹfa tabi oṣu mẹsan ki awọn to tun tu Ile Igbimọ Aṣofin ka ki awọn si tun pe fun ibo Atundi miran lọna ti yio mu iwuri wa fun gbogbo awọn enia,ki iṣe ni Ipinlẹ yi nikan ṣugbọn yika gbogbo agbaiye.

rara, awọn nikan ni awọn yio da Ijọba Ipinlẹ na ṣe bi o ti wulẹ ki o ri.

Nitori idi eyi, ni Gomina na ti ṣe kọ lati pe ipade Ile Igbimọ eyiti nwọn ṣe ni ọsẹ meji sẹhin yi, nitorina ni Gomina na si ṣe kọ ti ko fi lọ si ipade ti nwọn ṣe ni ọjọ na.

Nigbati Gomina na kọ jalẹ wipe on ko ni pe ipade ọjọ na ni ile iṣẹ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba pe ipade na wipe lati ile iṣẹ Gomina ni aṣẹ ti jade wa wipe Ile Igbimọ na yio ṣe ipade gẹgẹbi Ofin eto iṣelu eyiti o fun Gomina na laṣẹ ati le pe ipade.

Ṣugbọn nigbati nwọn pe ipade na, Gomina kọ ko si lọ si ile Igbimọ na lati lọ ba awọn ọmọ Ile Igbimọ na sọrọ gẹgẹbi aṣa rẹ ati gẹgẹbi Ofin eto iṣelu eyiti o fun Gomina na lati ṣe, ati bi o si ti maa nṣe ẹhin wa siwaju asiko yi.

## ILERI

Ṣugbọn bi Gomina na ti ṣe sọ ọrọ na ati imọran na to, awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ko gbọ gbogbo ohunti o nwi fun wọn ni ọjọ na, nwọn si sọ wipe awọn ko ni gba imọran, ti Gomina nda fun awọn

Nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ na ti kọ ọrọ si Gomina Ipinlẹ na lẹnu ni o bati ṣe pinnu ninu ọkan rẹ pe, on ki yio tun ni ohunkohun ṣe pẹlu Ijọba Iwọ Orun mọ tit ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ yio fi gbọ ohunti on wi pe, ki nwọn o ṣe ati \\\



**Oloye S. L. Akintola**

Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

ti nwon yio si fi ṣe ohun na pẹlu.

Nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti ṣe ipade na tan ni nwọn ti bẹrẹsi ma a ṣe ipade lori ọro ti Gomina na sọ, lori bi gbogbo nkan ti ṣe nlọ si ni Ipinlẹ Iwọ Orun ati on ti o sọ wipe ki awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ni Ipinlẹ na jijọ pin aye ijoko awọn Minista ninu Ile Igbimọ na.

A gbọ wipe nibiti nwọn gbe nṣe ipade na lọwọ, awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ da si ona meji, awọn kan faramọ imọran ti Gomina na da, wipe o dara, awọn kan si lodi si imọran na wipe awọn ko faramọ imoran na rara.

WO OJU EWE KẸFA

# NWỌN TUN YINBỌN PA ỌLỌPA MEJI NI ILE-IFẸ

ILE—IFẸ:- 'Kaka ki o san 'ara iya aje o fi ọmọ rẹ bi Obinrin, eiyẹ nbi lu ẹiyẹ' ri ohunti o ṣẹle ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ọjọ ti awọn enia Ipinlẹ ni ti dibo ni ọjọ o Aje ti iṣẹ ọjọ kọkanla oṣu kewa ọdun yi jẹ eyiti o fi jẹ pe Ọkeaimọye enia lo ti di alaini ile gbe ti nwọn ti di alaini aṣọ lara ti ogọrọ enia ti padanu ẹmi wọn lori rogbodiyan ti eto abayọri ibo na da silẹ.

Ni kutukutu owurọ ọjọ ọjọ 'Bọ ti Iṣẹ ọjọ kerindinlogun oṣu yi ni irohin tun de ọwọ wa pe nwọn tun yin ibọn pa ọlọpa ti Ijọba apapọ Naijiria m e j i ati Ọkunrin kan eyiti a w ọ n Ọl pa ma run miran tun fi ara gbogbẹ n i n u ibọn ti awọn enia kan yan si wọn ni ilu kan ti nwọn npe ni Ajebandele ni ẹba Ile - Ife ni ọjọ ọjọ Ru ti iṣẹ ọjọ kẹdogun oṣu yi.

Irohin awọn Ọlọpa lati Ile-Ifẹ fi ye wa pe iṣẹlẹ na ṣẹlẹ nigbati nwọn ko awọn Ọlọpa lati ilu Ilesha lọ si ao-leko na lati ṣe e t o bi nwọn yio ṣe fi opin si ija nla kan to bẹ silẹ ni ilu na eyiti o fi le wipe awọn Ọlọpa na si gbera lati ṣe eto bi alafia ati ifọkanbalẹ yio ṣe p da bọ si ilu n .

Irohin awọn Ọlọpa na tun fi ye wa pe gẹgẹbi awọn Ọlọpa ti nwọn ko lọ si a uleko na lati ilu Ilesha ngbiyanju lati ṣe afara le ori omi kan eyiti awọn enia ilu na ti baje lati le ri ọna gba de ilu na ni awọn enia kan ti o wa ninu igbo ti nwọn si jẹ awọn enia ilu na ba bẹrẹsi yin ibọn eyiti enia meji si ku lesẹ ẹsẹ nibu awọn Ọlọpa na ti marun si fi ara gbọgbẹ ibọn.

Awọn Ọlọpa meji ti awọn enia na yin ibọn pa ninu ilu na ni nwọn npe ni M' Golli ati B Okpan chi

Irohin fi ye wa pe nwọn ti gbe oku awọn Ọlọpa na ji ti nwọn yin ibọn pa na lọ si ile iwosan lakulaku ti ilu Ile-Ifẹ lati lọ ṣe ayẹwo wọn

Irohin na tun fi ye wa ipe okunrin kan ti nwọn nu yin ibọn pa p lu awọn Ọlọpa mejeji na ni a gbọ pe awọn ko ti m o oruko rẹ ati pe awọn Ọlọpa marun ti nwọn tun yin ibọn fun ni irohin tun fi ye wa pe nwọn wa ni ewu ni ile iwosan ti ilu Ile Ifẹ bayi

Ṣugbọn ko si enit a awọn ọlọpa mu fun ohunti o ṣẹlẹ si awọn Ọlọpa na irohin fi ye wa pe nwọn ti tun ko awọn Ọlọpa miran lo si ilu na lori ohunti o ṣẹlẹ ni abuleko na.

Ninu irohin to tun de ọwọ wa ni kutukutu owurọ ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣẹ ọjọ kẹrindinlog n oṣu yi ni irohin ti fi ye Wa pe awọn enia kan dana sun Ọgbẹni Sunmọla Dada ti iṣe Osi Imam ti ilu Okun-Ọwa ni ẹba Ilẹbu—Ode ni aaye ninu ile rẹ ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi eyi o jẹ pe ni nu ile rẹ ni nwọn ti dana sun ti nwọn sun gbogbo ile Ọkunrin na pelu.

Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa fi ye wa pe ni kutukutu owurọ ọjọ na ni awọn enia kan ti ko si enit o mọ wọn lọ si ile Ọgbẹni Sunmọla Dada ti nwọn si dana si ile rẹ yi a eyti o fi jẹ pe Ọkunr n na si wa ninu ile pelu.

Irohin tun fi ye wa pe gbogbo ile na ni o si jo na patapata eyiti o fi jẹ pe Ọgbẹni Sunmọla Dada ti iṣe Osi Imam ko t ji nibiti sun si ki ina nla na to ṣẹlẹ ninu ilẹ rẹ eyiti Ọkunrin na si fi ko rgbako tirẹ ni owurọ ọjọ na.

Nwọn si ti gbe oku okunrin na to jo ku lọ si ile Iwosan lakitaku ti ilu Ijẹbu-Ode l t lọ ṣe ayẹwo rẹ ati pe awọn Ọlọpa ti bẹrẹ lati ma ṣe iwadi awọn enia ti nwọn dana sun ile Ọkunrin na:

Irohin wọn Ọlọpa ti ilu Ijẹbu - Ode fi ye wa pe o di enia mẹta ti awọn Ọlọpa ti ri mu ti nwọn si wa ninu itimọle ni Tẹṣan awọn Ọlọpa ti Ijẹbu - Ode lori ina ti nwọn da sun Ọba Kẹlẹko ti ilu Atan Iẹba Ijẹbu Igbo la ye ni opin Ọsẹ to koja lọ yi eyti o fi jẹ wipe Ọba na s jona ku bamubamu.

Ki awọn ọlọpa tori awọn enia mẹta mu lori Ọba na ti nwọn da a sun laaye ni eto iwadi ti awọn Ọ l ọ p a Ọtẹlẹmuyẹn ti nwọn ko lọ si ilu na lati Ijẹbu Ode bẹrẹsi ni iṣe eyiti o fi jẹ wipe awọn Ọlọpa na n r i n lati oju ile an si oju ile keji titi nwọn fi ri awọn enia mẹta na ko.

Awọn ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹn ti nwọn ko lọ si ilu tan lati Ijẹbu Ode l a t i lọ ṣe iwadi awọn enia to d a n a sun Ọba Keleko ti ilu Atan laaye nani Ọgbẹni Y i s a Jinadu ọkan ninu ọga awọn Ọlọpa si jẹ Asiwaju fun awọn Ọlọpa to lọ si ilu na.

Ṣugbọn ko si ẹnikan gbọ pe awọn Ọlọpa ri mu awọn enia ti nwọn dina s u n Ọgbẹni Sunmọla Dada laaye tit di asiko ti a fi n k o i ve yi.

# Ha Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils d ara pupọ An O dara lu gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu Ile ni kiakia orun rẹ si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun d radara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o ri erin mẹta yi n nw n mu un o

The Elephant mosquito Brand coils yi wa n ṣọbu nla ja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

## WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office

16, Bamgbose Street
LAGOS

# Ẹgbẹ UPGA Kan Saara Si Esua Lori Aye Rẹ To Fi Silẹ

EKO:- Gbogbo ọmọ ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) ni o ti bẹrẹsi maa yo nbo Ọgbẹni E E Esua ẹni to lọ ẹla amojuto eto ibo fun Apapọ Ijọba Naijiria fun ọna ọwọ iyi ati ẹyẹ ti o gba fi ipo re silẹ ni ọjọ ojo Bọ tiṣe ọjọ kẹdogun osu yi ninu ọrọ ti Oloye Fred Anyiam ẹniti o jẹ ọkan ninu olori (UPGA) sọ ni Eko ni ojo Ẹti tise ọjọ kẹtadinlogun osu yi ni o ti so ninu ọrọ re pe o jẹ iwa ti o dara julọ fun Ọgbẹni Esua nitoripe ẹniti o ba nfẹ isọkan ati alafia orilẹ ede Naijiria paapa iwọ Orun gbọdọ gba fun Esua lori aye rẹ to fi silẹ



Ọgbẹni E. E. Esua

Oloye Anyiam sọ pe "Ọgbẹni Esua ti fi ọna han gbogbo enia awọn ti o kan lọna kan tabi lọna miran lori ibo aiyederu ti nwọn di ni ọjọ kokanla osu kewa ọdun yi gbọdọ fi ipo nwọn sile gegebi Ọgbẹni Esua tiṣe

Ọgbẹni Esua ti yanju edeaiyede to sẹlẹ lori ibo na o si jẹ ki nwọn tu ibo na ka ki nwọn dibo tutun ni Ipinlẹ na

Oloye Anyiam ni awọn nfẹ a'afia ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣugbọn alafia na gbọdọ jẹ lori ọwọ ati alafia ti yio duro lori otitọ ati ododo otitọ ati ifẹ enia si enia"

Iwe kan ti a ri gba lati ọwọ ọjọgbọn Samuel Aluko ti o jẹ ala ga igbimọ ilana fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o wa ni ilu Enugu ni Ipinlẹ Ila Orun Naijira ni o ti sọ pe awọn ko ni gba Ijọba kijẹba ti nwọn ba fi ibo ti nwọn di ni ọjọ l o

Ọjọgbọn Samuel Aluko nsọrọ lori ipo alaga igbimọ alamojuto eto ibo ti Ọgbẹni Esua fi silẹ ni ọjọ ọjọ 'Ru tise ọjọ kẹdogun osu

O wa kesi Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Ọlọla Ọdẹleyẹ Fadahunsi pe ki otete le Oloye Akintola kuro nipo alakoso Ijọba na ki o si yan Ijọba Fedihẹ lati ma mojuto Ipinlẹ Iwọ Orun titi ti nwọn yio fi dibo miran ni ipinlẹ Iwọ Orun

Ninu ọrọ ti o fi yin Ọgbẹni Esua ni o ti sọ pe gbogbo ọmọluwabi enia ti o tun je olododo ni lati dupẹ lowọ Esua lori iṣẹ rẹ ti o fi silẹ

Ni ipari ọrọ rẹ ni o tun ṣe apejuwe kan pe a ko gbọdọ rán egun apa mọ iwa ibi ti Ọgbẹni Ian Smith ri ile Rhodesia nhu ni bati awọn enia dudu ti nwọn koto nkan kọ lati fun enia dudu ara-kunri nwọn lati ni Ijọba ti nwọn nfẹ fun arawọn,

Ọjọgbọn Aluko wa kesi awọn olori ọmọ ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA pe ẹ jẹ giri nisisiyi tabi ki ẹ wa ninu alafia oyin lailai.

---

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYAMIRIN** TỌNIK

AL E-BI-ALE Egbogi Tọliki jamonu, tilun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ d j fun Agbara ati Abẹbidan iṣẹ Ilera agbalagba Ọkunrin ati Obinringbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lasan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọ ailera gbogbo nyia ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹlọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di tun pafapata inu rẹ a jẹlọ ẹran ara rẹ ti o gbunjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni ugba yio sao pẹlu ioq m adeu brode o iyẹn d bıṣ



WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm ChurchStreet Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

ATI NI ṢỌBU

IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

---

## Angeina Super -- Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara Aṣẹṣẹ jade akan ako mọ ibiti o nlọ Ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin O tun wa fun irun didi ati kiko olowo o nmu irun ọkunrin pap ma dan ki o si jọlo O ma fun ara ni ẹwa akotun Awọ ara yio si yọ jade perepere.

Bi enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi Enia pupa kuku ti wa tẹlẹ.

Tere sare watabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o to tan ni West Afican Cosmetic Industries" 35' Ọmọwunmi St Ilẹhin District Council Mushin ẹrọju ara ati irun nyin ẹtọ Owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila

---

## IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

I we yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue
Lagos, Nigeria (Leti Ọja Jankara)

# Olopa Meji Ku, Marun Fi Ara Gbogbe, Nwon Sun Okunrin Kan Laaye

AJEBANDELE:-Irohin awon Olopa ti o wa ni Ilesha fi ye wa pe nwon ta Olopa meji ati okunrin kan ni ibon ti nwon si ka ni oju ese ni ilu kan ti ko jin si Ile Ife ti oruko ilu na nje Ajebandele ni ti ojo ojo'Ru tise ojo yi ti awon Olopa miran si farapa awon wa ni ile ogun kedogun osu to wa ni Ile Ife bayi

Irohin awon Olopa fi ye pe ija kan lo bere latri awon egbe oselu meji ni gbati agbara awon Olopa to wa nibe ko ka oro na mo ni nwon ba ranse si Ilesha lati lo ko awon Olopa si wa ki awon Olopa to ti Ilesha de awon ara ilu na ti ba afara ti o wa ninu ilu na je

Bi awon Olopa ti de ibi afara yi ti nwon ri pe o ti baje ti nwon fe sure se eyi ti awon gbe de ilu na bi awon Olopa ti ba sile ninu moto won ti nwon nwa ona lati se afara miran ni nwon rgbo ibon lotun losi lati inu igbo logan awon Olopa ti ibon ko ba fi ese fee ti oro na di bo ba lo ya fun mi ni ojo na.

Awon Olopa meji ni oku bamubamu nibe ti awon Olopa marun fi ara gbogbe nwon ti ko gbogbo won lo si ile oogun ti o wa ni Ile Ife fun ayewo Dokita ti nwon si nse itoju awon ti o fi ara gbogbe lowo bayi ni ile oogun ti o wa ni Ile Ife

Oruko awon Olopa meji to ku na ni Ogbeni M Go na ni Ogbeni B Okpan chi awon ko si ti mo oruko eniti o tun ku pelu awon Olopa na bayi

Owo Olopa ko ti te awon eniti o se ijamba na beyi sugbon nwon ti da awon Olopa si ilu Ajebandele ba yi lati pana ija ti o wa ni nu na irohin ti a tun gbo ni pe ilu na ti dake bi isa oku

Irohin tun de owo wa lati Ijebu Ode pe, nwon tun dana sun okunrin kan mole ninu iyara re nigbati o sun ni ojo kedogun osu yi, oruko okunrin na ni Ogbeni Suamola Dada, eniti o je Osi Lein mu ti ilu Okun - Owa Ieba Ijebu Ode:

Irohin fi ye wa pe, awon kan ko arawo ojo ni owu ro ojo na ti nwon si lo si ile Ogbeni Dada, ti nwon si dana sun ile na, ogbeni Dada wa ninu ile nibiti o gbe ti sun lo patapata, ki o to taji ile ti gba fun ina ti eni ti k si lo u ti ko fi ri ona jade ti o fi jona sinu ile, ile paapa jona di eeru.

Nwon ti gbe oku Okunrin na lo si ile oogun ti o wa ni Ijebu Ode fun ayewo awon Dokita.

A tun gbo irohin kan lati Ijebu Ode pe, awon Olopa ti mu awon meta ti nwon lero wipe, nwon wa ninu awon ti odana sun oba Keleko ilu Atan ni opin ose t o koja yi.

Awon Olopa ti o lo si ilu Atan ti Ogbeni Yisa Jinada ti o je okan ninu oga awon Olopa ni a gbo wipe o fere je wipe gbo gbo ile to wa ninu ilu Atan ni nwon wo.

## YE IRAWO RE WO

AQUARS (Jan 22 Feb 20) Ise sise yio po fun o lonitori pepe wa tube ti yio fi se o pelu sagbon ire airotele kan yio de si o ni osan yi iwo yio si gbo irohin nipa ore re kan

PISCES (Feb 21 Mar 20) Egbogi kan ti o ti lo yio yonu die ni owuro yi nitoripe yio mu o ni otutu nigbati o ba seb oro ba [illegible] be mase na enikan wiregbe o dubule.

ARIES (Mar 21 April 20) Lati oni lo ara re yio ma tan siwaju, iwo yio si lo ajo osan pelu awon to nfe o iwo na si nfe.

TAURUS (April 21 May 20) Mase fi ara sile fun aare ti o fi, yio ipnu ki o si ni ogbon inu nitori enikan nibe ti yio mase lara re si [illegible] si o eyi data pupo

GEMINI May 21 June 21 Opolopo ohunti o je isoro fun o ni iwo yio le yanju patapata ti yio ri fun o aitele run iwo yio si aburo o kan lati ojo ajoji enia kan

CANCER (June 22 July 22) Iwo yio mo ni ara re wipe a ti gbo enu nla kan kuro ni ejika re, tobe ti ara re yio ya lati se isekise.

LEO (July 23 Aug 22) Iyogbon kan si mbe nile ti o nfe amojuto ni owu yi, sagbon ki o mase ki ibi ara si nitoripe ti ola na yio soro, mase ti lo gbogbo ogbon ori re sile tan.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ire yio kan o lara ni owuro yi, sugbon ni igbati osan yio ba fi po, aare le de si o, ohun ohun ti o b si lo s, alafia yio de.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ire mbe o repete loni, ti yio si tele lotun pe okan re bakan a ni yio ri ni akok san [illegible] ki o si jeki [illegible] ori re pe.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Wahala ati idamu yio de si [illegible] ki o se sun ki o s [illegible] ba le bi o ti wu ki o ri [illegible] fun o lonakona

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ohun kan ti o nse o yio po si [illegible] ko le [illegible] ohun kan ti o ngbero yio ni ilosiwaju

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Dapo lowo ero ori re ti [illegible] iwo yio [illegible] yio je ki ona re jin


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

### "CYCLEVEN"

Arun Jedijedi je okan ninu amodi ti o buru ni patak fun Okunrin ti o si lagbara lati se iwosan re patapata.

Opolopo egbogi ni nwon nta kakiri ode nisisiyi ti won a ma polowo won fun iwosan re sugbon boya la le ri mewa ninu ogorun ti o le se iwosan arun yi daradara. Awon elomiran lero wipeboya bi awon ba lo si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati o nusu ku nipa be awon o bo lowo re palapata

Sugbon awa ko ro bere rara: Lenin odun nie iyonu re yio sitan ma bere baka na, Orisirisi Jedijedi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ma se igbonse dede tabi lojojumo, elomiran n pa ijoko ni ojukanna selu lojojumo tabi gigun keke yiogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa jije Suga tabi oniruru ohun adidun papoju. Jedijedi orisirisi ni o wa ewo ni tire? Bi o ba nyo jade ninu olusa ta ti o ba nmu wa lehin igbo se tabi ba uyo ti o ba se igbonse tan ni, tabi ti ori n o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa ide re ko ki o si dinwo o isi meta ninu di u wipe iwo yio bo lowo Je i p tipatarslaoja yio de si ekeji re ko si ninu gbogo begbogi or ile Nsira Bere re ni:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P O Box 333

# Nwọn Gbogun Ti Awọn Ọlọpa Ni Ipinlẹ Iwọ Orun

ILE IFẸ:— Awọn irohin ti o nde ile iṣẹ wa lati ọwọ awọn oniwe irohin wa ti o wa kakiri Ipinlẹ Iwọ Orun ni a ti ngbọ lọ un losi pe awọn enia ti bẹrẹsi gbe ogun ti awọn Ọlọpa kakiri Ipinlẹ Iwọ Orun.

Irohin ti a gbọ lati Ile Ifẹ fi ye wa pe; ni ilu kan ti ko jinna si ilu Ile Ifẹ ti o njẹ Ajebandele ni a tun gbọ pe nwọn yinbọn pa awọn Ọlọpa meji ni oju ẹṣẹ, a gbọ wipe, ija kan bẹ silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ati UPGA, ngbati ija na pọ ti ọrọ awọn Ọlọpa ti o wa nibẹ ko ka ni nwọn ba sare lọ ko awọn Ọlọpa lati ilu Ilesha si wa, ṣugbọn ki awọn Ọlọpa to de ni awọn enia ba lọ ba afara ti o wọ ilu na jẹ.

Bi awọn Ọlọpa ti nbọ lati ilu Ilesha ti nwọn de ibi afara na ti nwọn ri pe o ti bajẹ were ni nwọn ti sare ade ninu mọto wọn, ti nwọn si nfẹ tun oju afara na ṣe ni airtẹlẹ ni nwọn bẹrẹsi ... bọ ibọn lọtun losi ninu igbo ti o yi itẹ ka, ni awọn Ọlọpa na ba bẹrẹsi ta ibọn ti nwọn si inu igbo na, ṣugbọn nigbati ọwọ ibọn ti awọn ti o wa ninu igbo du awọn ọlọpa ni awọn ọlọpa na ba siya ti nwọn ko duro gbọgbẹ.

A gbọ pe, awọn Ọlọpa meji ni o ku ni ojo kanna, ti ẹnikan si tun ku ninu awọn enia ti ọlọpa ta ibọn mọ, a ko ti mọ Oruko rẹ bayi ṣugbọn oruko awọn ọlọpa ti o ku na ni awọn Ọgbẹni Goli ati Okparashine, awọn mẹta ninu awọn Ọlọpa ti o fara gbọgbẹ si ti ku sinu ile oogun to wa ni ilu Ifẹ.

Ni Oke Owena ati Oba lutetodo ati ni Ifẹ opolopo ile ni awọn enia kan sọ di eeru patapata.

Ni Ilesha Olori ẹgbẹ Dẹmọ kan ogbẹni Sunday Ẹruko ... ni nwọn sare gbe lọ si ile oogun nigbati awọn kan ta mọon nigba a i y a ni Okesha agbegbe kan ni Ilesha.

Ni ilu Apomu ni Ikun Ọsun ... awọn tu ... ti pa Ọlọpa kan ti nwọn ko si mọ ẹni to pa Ọlọpa na bayi, irohin miran tun so fun wa pe, opolopo Ọlọpa ni o ti fara gbọgbẹ nigbati awọn kan lọ kolu won.

Ni Agosasa ni Ẹkun Ẹgbado, ni awọn ti dana sun ile iṣẹ Ọlọpa Ijoba ibilẹ ti o wa nibẹ, ti ile iṣẹ na si jona di eeru bamu bamu awọn ọlọpa ti o wa lẹnu iṣẹ ni ọjọ na ni nwọn kọkọ fi iya jẹ awọn enia ki nwọn to fi ina bọ ile iṣẹ nwọn, ti nwọn ko si ti mọ ẹni ti o ṣe iṣẹ ibi na bayi.

Nwọn tun sun ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti oruko rẹ njẹ Ogbẹni Fasasi ni ilu Orile Oko ni agbegbe Ẹgba ti Ọkun rẹ na si jona di eeru, Irohin fi ye wa pe, awọn ti o dana sun Ọkunrin koko sa ni ade ni gbogbo ara na,

Moto lori ile ẹkọ giga kan ni awọn tun dana sun patapata ti moto na ko le fi ẹe tunṣe mọ, bẹna ni ni ile Okunowa ni agbegbe Ijẹbu ni nwọn tun dana sun okunrin kan ti oruko rẹ njẹ Ogbẹni Sunmola Dada ti nwọn tun dana sun ile rẹ pẹlu


# Kereo Kere o!
# Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na jẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamotase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọrọ soya tani pe ile fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, igbẹ sise, asiko ri igbonsẹ deede, inu lrun ngbo kugba ara wiwo, Ẹsan ri ẹhin didun sisan ati aikoriran kedere ko diro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ujak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa siso di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile meje abọ (7/-6 pere Igo kekere sile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Ana ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn;—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Sireet, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos



# ALEBIOSU BOOKSHOP

13 BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & Interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1 | To my Darling | 2 | To my Sweet Heart |
| 3 | ,, my Lover | 4 | ,, One I Love most |
| 5 | ,, my Boy Friend | 6 | ,, Husband |
| 7 | ,, my Wife | 8 | ,, my Sister |
| 9 | ,, Brother | 10 | ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,590 MONDAY DECEMBER 20, 1965 (2D)

## Awọn Ọlọpa Ri Oku Obinrin Kan

ABẸOKTA:-Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa ri Oku Obinrin arugbo kan ninu ile kan ni ilu Iro lẹba Ow de nibiti awọn Ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ meje ti ilu Abẹokuta ti sọnu lọse to kọjá lọ yi eyiti awọn Ọlọpa ti ri oku ọkan ninu awọn Ọlọpa meje to sọnu na,

Ninu irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa ti ilu Abẹokuta ni nwọn ti ṣe alaye pe ninu ile ti awọn enia inu rẹ ti salọ nigbati iṣẹlẹ to bẹ silẹ yi tị ṣẹlẹ ni nwọn ti ri oku arugbo Obinrin na ti o fẹ ti ra siuu ile na atipe oku arugbo Obinrin na ni idin ti nyọ lara rẹ.

Irohin awọn Ọlọpa na tun fi ye wa pe nwọn ko tí mo arugbo Obinrin na titi di asiko ti a fi nkọ irohin yi nitoripe o ti nyọ idin lara,

Irohin awọn Ọlọpa na fi ye wa pe awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ti nwọn ko lọ si ilu na lati Eko, Ibadan ati Abẹokuta lọ ri oku Obinrin na ninu ile na atipe awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ti nwọn ko lọ si ilu na ti ṣe alaye pe awọn si nwa oku tabi aaye awọn Ọlọpa Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta ti o sọnu lọsẹ to kọja ati pe nwọn ki ti ri nwọn bayi.

# IJA NLA BẸSILẸ LARIN GOMINA ATI AKINTỌLA

### Lati Oju Ewe Kini

Awọn kan ninu awọn omo ẹgbẹ Dẹmọ na so wipe, bi Gomina na ba kọ lati gbo ohun ti awọn nsọ fun un, ko tuo si ohun miran ti awon le ṣe mọ ju wipe ki awọn wa ọ n a ti awọn ba le gba ki wọn si tete ro Gomin, na loye lọ nisisiyi ki o to pọ ju.

Ṣugbon nigbati irohin kan Gomina na ninu ile rẹ lẹhinti awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ṣe ipade tan, Gomina na sọ wipe, ki o to di wipe awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ikede wipe awọn ro On loye, on ni On yio kọkọ tu Ile Igbimọ na ka na ti On yio si paṣẹ wipe ki nwọn lọ tun ibo na di, ki awọn wa wo ẹniti yio wọle ninu ibo atundi na.

A gbọ pe nigbati oro na de si etigbo awọn Ọba alade ati awọn Ijoye yika Ipinlẹ Iwo Orun, nwon ti dide si oro na ko ma ba ṣe lọ si waju, ki awọn si tete pari oro na larin arawon,

Nitori oro yi ni Gomina ko fi lo si Ile Igbimo na nigbati awọn ṣe ipade ti o si ti pinnu ninu okan rẹ pe. on ko ni yi pada ninu ipinnu on ti ṣe yi, ohun yowu ki awon enia le so, nitoripe ko ni jẹki Ipinlẹ Iwo Orun wa bajẹ lori on.

A gbo pe gbogbo awon Ọba, Ijoye ati awọn omo Ijẹsha ni nwon ti bẹrẹsi ma kowe si Ọlola Fadahunsi pe, ki o fi ipo rẹ silẹ ki o ma si ṣe ṣe Gomina Ipinlẹ na mo.

Larin awọn ọmo ẹgbẹ Dẹmọ, awon kan nso ninu won wipe awon fa ramo imoran Gomina wipe, ki awon ni Apapo Ijọba ni Ipinlẹ na, fun igba diẹ titi ti awọn yio fi tun ibo di ni Ipinlẹ na.

Nitori oro yi, awon enia na tun da si meji, nigbati awon kan faramo imoran na, awon kan si ko jalẹ wipe awon ko gba imoran na, ẹgbẹ Dẹmo nikan ni ma a ṣe Ijoba Iwo Orun Naijiria.

Irohin ti ye wa pe, o ti le ni ẹdẹgbẹta (500) enia ti o ti ku lati igba ti awọn ti dibo tan ni Ipinlẹ Orun lẹnu igbati nwọn ti dido yi ti nwọn si ti jo ọpọlọpọ awọn ile ati dukia miran olowo iyebiye danu



Ọlola Adesoji Aderẹmi Ọni Ifẹ

A gbo pẹlu pe awon ẹgbẹ oṣelu kan ti lo jo ile Ọlola Fadahunsi eyiti o wa ni Mushin ati eyiti o wa ni ni Ilesha nitori oro ibo ti nwon di koja lo na

Ko si ẹniti o le so kini ohunti yio tun ṣẹlẹ ni Iwo Orun lẹnuloloyi nitori ede aiyede ti o tun wa larin Ọlola Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ati Oloye Akintola nisisiyi

Ṣugbon awon Ọba, ati awon Ijoye ti dide si oro na, nwọn si fẹ pari rẹ larin arawon ki awon ara ita ma ba ṣe gbọ ọrọ na titi ti wọn yio fi pari rẹ

Ṣugbọn ohunti a ngbọ ni pe awon kan ti dide ti won si fẹ pari ija ti o wa larin awon omo ẹgbẹ UPGA ati ẹgbẹ Dẹmo, ṣugbon bi a ba ti tun gbo oro na si, ẹo tun ma gbo o

# Ofale Kan Yo Ehin Ọrẹ Rẹ

### Lati Oju Ewe Kini

gba ọwọ ọrẹ sọnu siwaju ṣugọọn bi o ti fi ipa mu ọrẹ rẹ na lati fẹ fi ẹnu kan an ni ẹnu, nṣe ni ọrẹ rẹ gbe ẹnu na sa fun un, ti o si lọ fi ẹnu na lu opo ina manamana ti o wa nibiti nwọn duro si, ehin meji si ṣyọ jade ni ẹnu ọmọbinrin na.

Were ni gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni tosi ba jade nigbati nwọn gbọ ariwo ẹkun ọmọbinrin na ti o nkigbe ni arin ode, nigbati awọn enia n gbọ ohunti o ṣẹlẹ si awọn mejeji ni nwọn ba sare lọ pe awọn Ọlọpa ni Tẹṣan wipe ki nwọn yara tete wa gbe ọmọdebinrin na, ẹni ọdun mẹdogun lọ si iwosan fun itọja.

Ni awọn Ọlọpa ba mu ọdaran na lọsi ile ẹjọ nwọn si gbe ọmọbinrin na lọ si Ile Iwosan fun itọju awọn Dọkita. Adajọ ti yẹ gbigbọ ẹjọ Ọdaran na si ọjọ iwaju titi di igbati ọmọbinrin na yio fi jade ni ile Iwosan ti awon mejeji yio si wa sọ ti ẹnu wọn niwaju adajọ.

Bi nwon ba ti pari ẹjo a si, ẹo tun ma a gbọ o.



Alhaji D S Adegbenro

Printed & Published Mopupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 20/12/65